# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No 778, MONDAY AUGUST 24, 1964 (2D)

## Adajọ Ni Ki Ọkunrin Kan Fi Ọgọjọ Pọun Tanran

IBADAN;- Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ile ẹjọ kekere ti Ibadan ni ki ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ NNDP Ọgbẹni Ademọla Odumosu lọ fi Ọgọjọ Pọun tanran tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mejidinlogun fun ẹsun pe o lọ ba awọn ẹru ṣọbu ile Ọgbẹni kan jẹ Ọgbẹn Fatai Odunowo ni adugbo Amunigun, ni Ibadan ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi.

Ninu awọn ẹsun tt awọn Ọlọpa fi kan Ọkunrin ọdaran na ni pe o lọ kọlu Ọgbẹni Fatai Odunowo ni ile itaja rẹ nibi to ma nfi awo gramafonu (Grammaphone Records) ti ọdaran na si ba gbogbo nkan to wa ni ile itaja Ọgbẹni Odunowo jẹ.

Adajọ ile ẹjọ na si da a lẹbi lori ẹsun pe olọ kọlu Ọgbẹni Fatai Odunowọ eyiti o fi ba Ọgbẹni na lori asun ti ko fi ẹs; mulẹ dada.

Ninu idajọ ile ejọ na sọ fun ọdaran na pe ki o lọ fi ọgọjọ ponun tanran tabi ki olọ si ẹwọn oṣu mejidinlogun.

Irohin fi ye wa pe Ọkunrin ọdaran na ko gba pe on ko jẹbi ati pe kosi pe ẹjọ ko tẹmi l'ọrun nigbati adajọ ṣe idajọ rẹ lori ẹsun" na.

### BENSON SỌ PE:

# AKINTỌLA, BẸBẸ FUN IDAṢILẸ AWOLỌWỌ

EKO :- Oloye T. O. S. Benson Minisita alamojuto eto irohin fun Ijọba Apapọ Naijiria ati igbakẹta olori ẹgbẹ Alakukọ kesi oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Ilẹ Naijiria ati olori ẹgbẹ Dẹmọ NNDP lati ran on lọwọ ninu ẹbẹ lati da oloye Ọbafẹmi Awolọwọ silẹ ni ọgba ẹwọn eyiti ile ẹjọ giga kọ ẹbẹ ẹwọn ọdun mẹwa rẹ silẹ lori ẹsun iditẹ ati idoju Ijọba apapọ ilẹ Naijiria bolẹ.



Oloye S. L. Akintọla

Oloye Benson sọ ninu ọrọ rẹ pe o da on loju pe ki eto Ijọba rere ati alafia to le wa ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria afi ki awọn Olori ẹgbẹ oselu to wa ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tete fi opin si ija to wa larin awọn olori ẹgbẹ oselu na.

Oloye Benson tun fesi ọrọ ti oloye S. L. Akintọla sọ pe ara ni on (Benson) fi nṣe ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti oloye Benson tun nfi ọkan ṣe ẹgbẹ Demọ (NNDP.)

Oloye Benson si



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO



Oloye T. O. S. Benson

dahun pe loni gẹgẹbi o ti ṣe ri lana na pe on jẹ enia kan pataki ninu ẹgbẹ Alakukọ ati pẹe ọkan ninu awọn olori ẹgbẹ na. Oloye Benson si sọ ninu ọrọ pe irọ patapata ni gbogbo ọrọ ti Oloye S. L. Akintọla sọ mọ on lori ọrọ rẹ.

Ninu esi ọrọ ti Oloye Richard Akinyẹmi Alakoso eto oye fun Ijọba Iwọ Orun tẹlẹ ri pe nṣe ni o yẹ ki awọn ti nṣe Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria kuro patapata lori ikuna wọn nibi ipade apapọ ilu awọn enia dudu eyiti Oloye Akinyẹmi sọ pe Ijọba ilẹ Naijiria kuna lati fi ijoko ipade na si ilẹ Naijiria ati le jẹ ki ọmọ Naijiria jẹ akọwe gbogboo apapọ ipade awọn ilẹ enia dudu na (O. A. U.) Oloye Benson sọ pe iru ọrọ ti Akinyẹmi sọ na nṣe ni o yẹ ki a gba si gẹgẹbi alaimọkan sọ ati enia kan ṣa ti ko ronu lati sọrọ.

# YẸYẸNATU

## ONIYEYE EKO

Yẹyẹnatu :- Olotu, ẹ ku ara ya, ẹku atijọ, ẹ ku ati
Olotu :- Nibo lo ti lọ Yẹyẹnatu ?
Yẹyẹnatu ;- Ha, mo lọ si Kaduna ni mo wa ya ni Ibadan
Olotu ;- Howu o nsowo nisisiyi ni ?
Yẹyẹnatu :- O yes owo ni lootọ şugbọn ılu ni m• nta kiri
Olotu :- Ilu bawo ?
Yẹyẹnatu :- Emi pẹlu NNDP polowo ilu wa lọ ni
Olotu :-B i burẹdi tabi bawo ?
Yẹyẹnatu :- Bi tuwo, a si ti ri ẹni raa
Olotu :- Tani wa ra a?
Yẹyẹnatu :- Ẹ tun nbi mi ? NPC la ta a fun ? Ọja na tilẹ bọ si gan ni,
Olotu :- Igba wo ni iwọ, di ọmọ ẹgbẹ Dọmọnu paapaa ?
Yẹyẹnatu :: Igbati mo ni owo lo ni mo ba sọ pe ki nwọn mu asia wa.
Olotu :- O fẹ sọ pe eni ba sọ bẹ, nwọn a fun owo
Yẹyẹnatu :- Ko si ohun ti nwọn ko le sẹ fun oluwarẹ nile paapaa:
Olotu:- Iwọ ri ẹnikan ti nwọn sẹ bẹ fun ri ni ?
Yẹyẹnatu : Nko ri i ri sugbọn mo gbọ pe nwọn nfu enia ni owo rẹpẹtẹ lemi na ba ni mo fẹ şe ẹgbẹ. Nwọn ko ifun mi sa
Olotu : Tani iwọ wa fẹ dibo fun lakoko ibo ?
Yẹyẹnatu : Ha, ẹtuu nbi mi ni? AG ati NCNC ni kẹ
Olotu : Iyen to fẹ gbowo lowọ NNDP
Yẹyẹnatu : Ohunti gbogbo wa nsẹ nisisiyi ni yen Şe ni 1959 Hausa gbowo lọwọ AG nwọn dibo fun NPC lọdun yi awa na a gbowo NPC a di o fun AG
Olotu : Ha awọn enia wa ko le şe iru nkan bẹ
Yẹyẹnatu : Nwọn ti kọgbọn nisisiyi Awọn Oba to gbẹ eh n fun Akintola ni ijelo lo naba kọbọ osu Bi o ba wu wọn ki nwọn tun dibo fun. Ko ni ya wa lẹnu nigbati F a n i Kayọde ba di kabiyesi lẹh n ibo
Olotu : Yẹyẹnatu o jẹ sọra rẹ
Yẹyẹnatu : Nko bu ẹnikẹni kẹ
Olotu : Şe o mọ pe onikalu ku lọ nsọra rẹ nisisiyi ?
Yẹyẹnatu : Lootọ ni ko ma ba de jẹ ki npẹnu mọ nko lowo lọya
Olotu ; Eru ẹjọ nba rẹ ?
Yẹyẹnatu : O to bẹ o Eni Sango ba toju rẹ wọlẹ ni ko ni bu Ọba koso mọ
Olotu:- Şugbọn ko y ẹ ki o bẹru.
Yẹyẹnatu:- Nitoripe?
Olotu;- Sebi o ni o lẹşẹ
Yẹyẹntu:- Lootọ ni, şu gbọn ko de Ikoyi
Olotu:- O ko lẹşẹ n i yen
Yẹyẹnatu:- Ha, nko gbadu ra k i nlẹşẹ d e Ikoyi nisisiyi nitoripe ọjọ ti enia ba na ẹşẹ de Ikoyi ko ni pada sile.
Olotu:- Nitori kini
Yẹyẹnatu:- Nwọn nru enia de ibẹ ni.
Olotu:- Nonsesi ọrọ omugọ lo sọ yen. Gbogbo awọn to wa ngbe Ikoyi nkọ şe oku ni wọn ni?
Yẹyẹnatu:- Şẹ ẹ oe itẹ ri?
Olotu:- Yẹs kẹ
Yẹyẹnatu: A Bright, şe arin enia n i nwọn ngbe?
Olotu:- Rara, şugbọn ki işe arin oku
Yẹyẹnatu:- Bi enia ko ba gbe arin alaye, arin oku lo ngbe i i yen
Olotu:- Iwọ p ẹ l u awọn alaigbọn ni ọ k a n
Yẹyẹnat:- Şe awọn bi oniwe irohin
Olotu:- Awọn yen ko gbọn ni?
Yẹyẹnatu:- Ti n w ọ n ba gbọn nwọn a maa şe eke kakiri
Olotu:- Bawo
Yẹyẹnatu:- Eni ba ngbọ ọrọ ẹnikan to nsọ fun gbogbo aiye laifi ran nisẹ nkọ? Eke kọ ni bi?
Olotu - O jẹ sọra rẹ nitori a le Pe ọ lẹjọ
Yẹyẹnatu:- Şe alaigbọn ti agọ sọ d i ọlọgbọn bi ẹnyin na ni lọya a ti adajọ.
Olotu:- Bawo?
Yẹyẹnatu:- Şe bi ki adajọ to di adajọ a kọkọ se lọya, sebi lọya nmọ pe ọpọlọpọ igba ọtọ n i ofi ọtọ ni otitọ, adajọ a si da f n a fi otitọ silẹ
Olotu: Ọgbọn ni yen kẹ
Yẹyẹnatu:- O t i t ọ n i se ọgbọn on siri ni ọgbọn awọn o m u g ọ a r a ọgbọn na ni
Olotu:- Bi iru iwọ?
Yẹyẹntu:- Nigbati agọ npa awọn oşelu Ibadan ni Ijelo ti nwọn ni awọn gbọn nwọn da ẹ g b ẹ U. P. P. silẹ
Olotu: Şe nwọn k gbọn ni ışọ
Yẹyẹnatu:- Ti wọn ba gbọn nwọn ko ni da ẹ g b ẹ silẹ ki nwọn tuka.
Olotu:- Isọkusọ wo lo tilẹ
Yẹyẹntu:- Ko l e ye nyin. Mo nsọ practice bi mo şe ma a campaign fun A G ni, O dabọ

# Ọrẹ Aja Pẹlu Ẹkun

Lati ọwọ — AFỌLABI ỌLABINTAN

Hausa he ada loko igbo o nfun kakaki
Kenberi he ada lagi ji, o njo gangan
Tani ko mọ pada igbo a sọnu loko ọdun
Dẹmọ ẹkun ti ndọmọ ọlọmọ sinu igbo
Ẹgbẹ oşelu ti ntu ile kakiri
O wọlu ọlọmọ nfọmọ Lati
O wọle kaluku nfaramọra
Nitori ko gbọn, ko tutu lẹgbẹ Dẹmọ
Bo npania a fẹrin sẹhin
Bẹjẹ nbẹ ninu a ma a tutọ funfun
Dẹmọ to sọ gbogbo olori di idi ninu ile
To şe ngba apo loşu donikọbọ kanşoşo
Ẹgbẹ to tori ipo sọlu nu bi oko
T tori i ẹkufe nja ifẹ logun
Aja nbẹkun sọrẹ, a anu anu aja ı şe mi
Akukọ nfọgbe han kọlọkọlọ
Mo ma nkan ẹiyẹ.
Nitori ọrẹ aja pẹlu ẹkun
L'Akın ati Sadauna npilẹ
Ọrẹ akukọ pẹlu kọlọkọlọ ati Dẹmọ
Nitori ohun to şe ila to ko lori
Ohun to şe ikan to fi wẹwu ẹjẹ
Ohun to şe Afẹnifẹre to nsimi lawujọ
Ko ni şaişe N P C lagbara lagbaja
Ti nfẹ gbi gbona şohun gbogbo
O b e şe bi fara ile, alejo nio
Obe şe ika fọba kan, alejo nyọ şeşẹ
Bo pẹ titi owo Obe a talairọnu
Bo pẹ titi ohun to pa wọn pọ
A tun tu wọn ka lawujọ


BERE EGBOGI ARỌN

## "VERMZYN"

Ojulowo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn "ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARỌN latanlatan tabi arọn kinisa tioma mu id wọ wa fun ẹgbagbeje obinrin lati lyun tabi ti o ma nba oyun jẹ lara Obinrin.



Bẹsi ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti aran agbẹdu Igba-aya, ọna ọfun, sisọ lẹhin bi ake tabi aran oju pẹlu Meji irufẹ egbogi arọn yi kosi ri gbogbo ilẹ Naigeria jakejo işẹ rẹ si daju

AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe oti re eekọnọ ọwọ ati ẹsẹ rẹ daradara ki oto lo egbogi arọn yi gẹgẹbi awọn Jaman iti oşe ti juwe llo reo Fun awbalagba nikan n owa fun. Bere orisirisi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni şọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.

# IWE SI OLOTU

## Shoyinka ko Ṣe Ẹgbẹ Dẹmọ

Olotu jọwọ gba mi ni aye lati d hun si ibere kan ti o jade ninu iwe Iroh in Imọlẹ ti ọjọBọ ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi eyiti ogbẹni kan sọ ara rẹ ni Yoruba Ronu t i o ṣe ibere pe njẹ Ọgbẹni Shoyinka ti di ẹgbẹ Dẹmọ?

Eleyi ni lati fi han gbangba pe ogbeni J.o shohinka ko fi igba kan kuro ninu ẹgbẹ ọlọpẹ ati pe o le jẹ ohun to ya nyin lenu lati ri iwe rẹ ka ninu iwe to ngbenu-fun ẹgbẹ Dẹmọ imọle owuro ki o gbẹni Shoyinka ma kọ irohin si nu rẹ Gẹgẹbi iṣẹ ọgbẹni Shoyi-nka gẹgẹbi oniwe irohin ti o duro fun ara rẹ ko ẹniti ko sa lai le kọ a si iwe ironi rẹ yala ẹgbẹ A kukọ Olomi tabi D ẹ m ọ sugbọn ohun t! mo fẹ ki ẹ mọ ni pe Ọgbẹni Shoyi ka jẹ ọkan ni nu ẹgbẹ Afẹnifere ati pe ko fi igba kan kuro ninu ẹgbẹ na Ọ-gbẹni Shoyinka ni eniti amọ gẹgẹbi Alapara Ibadan ninu iwe Irohin Yoruba nigba kan iwọ ore ni lati fi ye nyin pe Shoyinka ki iṣe egbe Dẹmọ rara

Mo dupẹ pupọ olotu

Em ni

Bayọ Tiamiyu

Eko

## E la Eyi Yemi

Olotu jowọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ alakagba-dun lati bere ibere mi kekere yi lowọ awọn onkowe Irohin Imolẹ imo si fe nwon fun mi ni idahun kikun lori rẹ

Ọpọlọpọ igba ni ọrọ yi ti da ariyanjiyan silẹ larin emi ati awọn orẹ mi ṣugbọn a k mọ idahun rẹ

Ibere mi n a lo bayi Tani o wulo fun awọn obi rẹ ju ninu ọmọkunrin ati ọmọbinrin

Ẹ jọwọ, ẹ la ọrọ na ye mi o

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, ẹ ko ni siṣe o

Emi ni,

Ajao Amukoko

OMUPO

## Ole Pọ Ni Ọja Jankara

Olotu jọwọ gba mi ni aye ran-pe ninu iwe Irohin Imọlẹ rẹ alakagba dun ti nko wa ni ogbon ati oye lati kesi Ijoba ilu Eko f n amojuto ọja Jankara.

Ni arin ọja yi awọn de ati awọn arufin ti po nibẹ. Nitorina yio dara pupo ti Ijoba ilu Eko bale ṣe iranlọwọ lati ba wa le awọn ole yi kuro larin ọja Jankara

Bi enia ba mu owo ti o pọ o si inu oja yi enia ko ni mo igbati nwọn yio ja owo yi m on lara Iru iwa bayi ko si yẹ ki o wa ni il Eko

Mo lero wipe Ijọba Ibilẹ ilu Eko yio ṣe iranlọwọ lati ba wa le awọn ole wọnyi kuro

Olotu mo dupẹ fun aye ti e gb mi o ajinde ara yio ma je o

Emi ni

Abiodun Abe

Eko

## Mo Ki Olotu Iwe Irohin Imọlẹ

Mo dupẹ pupọ lọwọ Olotu iwe Irohin -Imọlẹ mo si tun ki pẹlu ati awọn osiṣẹ Iwe Irohin Imọlẹ oloyinyinmọmọ eyiti o jẹ Iwe akọkọ ni ede Yoruba ti o njade ni ojojumọ. Bi mo ṣe ki olotu pe koni rẹ nyin ati awọn oṣiṣẹ patapata.

Tẹlẹ ri iwe Irohin -- imọlẹ ki ifi ojojumọ jade tabi ki ifi ojo-jumọ de ilu Ibadan, Ṣugbọn ni-sisiyi inu awọn enia ilu Ibadan dun fun dide to ma nde ilu na lojojumọ bayi.

Iwe Irohin Imọlẹ si jẹ iwe kan to duro gedegbe ti ko fi ara mọ ẹgbẹ oselu kankan ati pe nitorina Iwe na si nta bi akara olororo atipe awọn enia ni ilu Ibadan ati agbegbe rẹ ma nsa-re ra Iwe Irohin -Imọlẹ.

Oluwa yio jẹ k i ọ w ọ nyin ma a lọ soke, iwaju ni ọpa ẹbiti nrẹ si iwaju ni ẹ o si ma lọ Amin

Emi ni

L. Animashaun

Ibadan

## Ilu Igbessa Nfẹ Omi Erọ

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ rẹ oloyin-mọmọ to nfun wa lọgbọn ati oye lati kesi Ijọba Iwọ Orun Naijiria lati fun Ilu Igbẹssa ni Omi Ẹrọ Abẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lati le tete fun wa ni Omi Ẹrọ nitori aiko ni O mi Ẹrọ ni Ilu wayi njẹ wa ni iya pupọ Omi Kanga ti awọn Ara Ilu nmu si nta ọpọlọ-pọ aisan wa si Ilu, nitorina a bẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun jọwọ ki tete ba wa ṣe eto bi Omi Ẹrọ yio ṣe de ilu wa laipẹ. Ilu Igbe-ssa tobi to bẹ ge tiko si ni Omi ẹrọ abuku ni eyi je lati gbo pe a ko ni Omi Ẹrọ A ko si nfi owo ori wa jafara rara, Ki ejọwọ tete ba wa fowo si o

Mo dupe pupo fun aiye ti ẹgba mi, Ọko Ọba ko ni sa nyin lese o Mo tun ki gbogbo awon osise Irohin Imole ku ṣe o.

Ọlorun Ọba na yio fona han gbogbo wa o.

Emi ni,

Idowu J. Durojaiye

IGBẸSSA

## Aṣoju Ilu Saro De Ilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ni apa osi aworan yi ni Ọlọla Alber. Mergai ti iṣe Olori awọn oṣelu Saro nigbati awọn gba a ni Alejo sinu Igbimọ ẹgbẹ gbogbo agbaiye.

Awọn Oyinbo meji ti o mba ẹsọsọ ni Sia Alec Douglas Home lọwọ osi ati Duncan Sandys lẹgbẹ rẹ.

AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee

Réf. N° 55. PHOTO

Free illustrated catalogue on demand



A Wonderful 15 Jewel lever shock protected, movement, non magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved.

Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial.

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque.

WINDSOR

19, Avenue de Lérins - Cannes, France

# Bi Ao ku Işe Kotan

LATI ỌWỌ J. A ATOYEBI

Mo ki Olọtu pupọ wipe ẹku Owurọ o, Oluwa yio jẹ ki ọwọ nyin ma lọ si oke o. Oluwa ko ni jẹ ki Ọkọ Ọba ki o ṣa nyin lẹsẹ o, Ẹjọwọ mo fẹ ki ẹ gba mi ni aye ninu iwe nyin Oloyinmọmọ ti nta bi akara gbigbona. lati gba awọn ara Olufẹ, ẹgbọn ati aburo ni iyanju pẹlu ọtọ mi kekere yi.

Nitori a nri ọpọlọpọ ẹba to je wipe nigbati nwọn ba rọ ohun ti o nṣelẹ si wọn titi li nwọn kosi mọ ohun ti nwọn yio ṣe nwọn a si pokunso tabi ki nwọn ge ara awọ lọbẹ tibi ki nwọn bẹ sinu omi. Ninu ti gba gba wipe awọn ko le da oh un kan ṣe lara ẹya ara wọn

Nigbati iwọ ba bẹrẹ ohun ti lọwọ Oluwa li iwọ ko re iranwọ rẹ olugbala yin

Nitorina iwọ ẹda maṣe ro ara rẹ pin ninu aiye yi nigbati o ba wa ninu isoro

Ranti pe iwọ k o lo da ara Eniti o da o ti mo wipe ẹri wọk ole ṣe alairi ohun o dara Nitorina ni o ṣe fi ọrọ rẹ tu o ninu iwe rẹ mi ti mo Nigbati o ba wa laye maṣe gba ero kero laye ninu ọkan rẹ Ma si ṣe gbagbe owe yi ninu iṣoro jẹki o ma ṣiṣẹ ninu rẹ nigbagbogbo

,Ẹnikẹni ti oba ka akọle yi yio mọ wipe owe awọn gaba Yoruba ni osọ bẹ ai kba si tun fi oju inu wo owe na, ao ri wipe owe ti ojinlẹ ni

Ni akoko. ẹjẹki a sọ ọrọ nipa owe na ohun ti itumọ re jẹ Owe na ha awọn enia ti ojẹ wipe nwọn ma nro ọrọ lọ si iwaju, ti nwọn ki i si ro lọ si ẹhin wi, ti okan iṣoro ba de ba wọn A wa ẹda gẹgẹb

Ẹleran ara ti wa laiye yi ko le ṣe alaiba iṣiri pade bi aini, airijẹ airiṣe ṣe airii aṣọ wọ tabi awọn ba wọn ni. Nigbati ati mọ wipe, ko le ṣe alai ma pade ohun bawọn ni a ni lati ma ro niwọn tun wosi iru ipo ti awa nigba a si t ọmọ nikeji wa a, Boya ti ti nwọn san ju tiwa lọ Nitorina ẹnyin ara ẹjẹki afia wa ni itẹkrun pẹlu ipokipo ti aba wa tabi ohun ti oba ṣẹlẹ siwa gẹgẹ bi igbesi aiye wa ba ti ri.

Nigbakuba ti a ba si wa ninu isoro bi a ranti ọrọ ti o sọ wipe ,ki a duro de irawo rẹ bi o tirẹ pe de duro bileri na tilẹ falẹ, sugbọn ko ni pẹ de ati eyiti o sọ wipe 'Eda to mọla kosi.

Nitori a nri ọpọlọpọ eda to jẹ wipe nigbati nwọn bi ro si sẹ sọ ireti nu rara Nitori bi ko ba si iku ti ko isi arun d judaju iwọ yio ri iyipa a rere. ranti pe bi o tilẹ koro loni o nbọwa dun lọla Nitori ẹ ẹki a duro de Oluwa nitori asiko tirẹ loju E jẹki a si tuka on yio si mu wa aiye e,

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ọwọ nyin yio ma roke O, Bi ekmi ko ba gba emi ẹ o ma gbadun mi ninu iwe nyin

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Iwọ le ri iyọnu diẹ nipa awọn ti o nfẹ lati ba asiki rẹ jẹ, ṣọra ki o si ma ronu daradara ki o to dawọle ohun kan.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Iwọ yio ri irohin kan gbọ lati ọna okeie wa ti yio jẹ mọ igbesi aiye rẹ. maṣe lera lati ṣiṣẹ kiakia bi aye rẹ ba ti de, nitoripe ijafara lewu.

ARIES (Mar 21-April 20) Gba imọran ti awọn ọrẹ rẹ ba fun ọ loni, Fi ara balẹ ṣe nkan bi o ba si ri pe fẹ ṣe idaraya, ṣe e nitoripe ki o ma ba si are.

TAURUS (April 21-May 20) Wahala ti o wa fun ọ nisisiyi, ire ni yio jasi foju silẹ si awọn aladugbo rẹ, ki o si mọ ohun ti iwọ o se,

GEMINI (May 21-June 21) Tọju ara re, iati ma fi aṣọ si ara, maṣe bọra si ihoriho lakoko yi kio si tọju ala fia re pataki ni alẹ, ija le ṣẹlẹ larin iwọ ati ọmọ abẹ rẹ fi suru si ki o si ma ibinu mọlẹ

CANCER (June 22 July 23) Iwa ti o nhu ni akoko yi dara jọjọ awọn irawọ Orun ngba fun ọ. ma jẹ faaji lọ sode ọpọlọpọ ori yio si ma sọkalẹ ni pipe.

LEO (July 24 - Aug 22) Ọjọ oni dara fun irẹpọ larin ẹbi, sagbara ki o ma si edekoyede kan larin iwọ ati ẹbi rẹ ki o si jẹki irepo ebi'e larin ebi rẹ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Maṣe jẹ Oniwọra tabi anikanjẹ anfani ti o si nje lọwọlọwọ yi, nfẹ didaro.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Idamu kan ti o ṣelẹ si ọ, o je nipa irankiran ti o nlọ wo, ma ba gbogbo enia sọre, ki o ma si ṣe ri enikeni sinu tabi yan ọdi.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ko h n re nijanu, ki o ma si ṣe ta awọn ọga rẹ dapar , Bi nwọn ba paṣẹ fun ọ maṣe fi wọn ṣe yẹyẹ, bibẹkọ, o le tilẹ ba alamori re jẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Iwọ yio se orire niwọn bi ọrun ba wa ai oju sanma, ṣugbọn ṣọra nibi irankiran niwo ki o ma ba ti ibẹ ba gbogbo nkan jẹ fun ọ.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Jẹki iun rẹ tutu, ki o ma si ṣẹ gbọju gangan si awọn aladu gbe rẹ, Bi o ba taku si ọna tirẹ, ti o si kọ lati ṣe konupiwada iwọ yio ba gbogbo ọna rẹ jẹ.


# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



Aworan ẹgbẹ yi fihan g ban Bba ibiti Jẹdijẹdi rẹ b wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nig bagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma be ṣe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi je ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ta a polowo awọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la le ri mewa ninu awọn egun ni o le ṣe iwosan arun

"CYCLOVEN"

yi daradara, Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile iwosan lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omusu ku nipa be awọn o bọ lọwọ re patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara lehin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bere bakanna Orisirisi Jedijedi ni o wa, Ekini ti o bere nipa aiko ma ṣe igbọsẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijẹko ni ijẹkanna pupọ ojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ elomiran ẹwẹ eran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi di orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omuṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnse jtabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣe tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ ko si danwo risi meta daju wipe iwọ yio lọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia lo de ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gbigboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICENE STORES
Tinubu Square Lago

Adedun Chemist
14, Workeman Street, Yaba

Waterloo Medicine Store;
8, Palmchurch Stree Lagos P O Box 333
Phone: 22878 Najeria (Oja Ita Faji

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE AUGUST 24 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| ẸKO ATI AGBERẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrẹkoko, Aṣu, Wasinm, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjau Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu Ogere Irolu Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Oja-Ọdan, Sunwa Iboro |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ IṢẸGUN AUGUST 25 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ọbun—Eko, Ojuwoye, Ikosi Ẹpẹ Atan, Agbabo, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Pẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta, Ijaiye—Ọrilẹ |
| IJẸSHA | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe Iṣara, Imọdi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọọ, Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado—Odo |
| EKITI | Igosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ'RU AUGUST 26 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUT | Mushin, Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ Omi Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwn Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Ido ọ Iloko |
| ẸGBA DO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ AUGUST 27 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajọ |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọ Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun, Lasilo Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ẸTI AUGUST 28 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Oyingbo, Ijoko, Ibẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ Ogunjau, Motẹlẹlẹ, |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaoṣu Ogere, Irolu, Itelu Ode-Rẹmọ Oyingbo |
| JẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunw Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan. |

## ỌJỌ ABAMẸTA AUGUST 29 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Iṣabọ Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| BADAN | Fẹdẹgbo, Oyedẹdeji Ogburo, Ẹgbẹ Babalokuta. Ijaiye-Ọrile |
| IJẸBU | Ilishan, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ Iọbaimuroko, Erinm |
| ẸGBADO | Ayetoro Ado Odo |
| EKITI | Egosi Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ AIKU AUGUST 30 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Mushin, Badagry Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun —Ọwa, Ẹruwa Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko Itoko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AJE AUGUST 31 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ikẹja, Agege Ebute—Ikorodu Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imode |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilọ-Idiẹmi |
| EKITI | kemẹsi, Ifaki. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati ọwọ DJO'NGBORO

### IBADAN

Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti san owo to, to bi £15,000 fun ile k kọ ile-ẹkọ giga kan ni Awẹ lẹba Ọyọ Irohin na fi nye wa nibi ẹyẹ eto ikini ku abọ eyiti awọn ara ilu Awẹ fi ki Alakoso eto ẹkọ fun ijọba ipinlẹ Iwọ-orun Naijiria Ọgbẹni Daniel Olumofin ninu Ọsẹ to koja.

### OWERKI

Awọn ọmọ ẹgbẹ ti a npe ni Mbaitoli Federal union ni agbegbe Oweri sọ ninu ipe ti awọn ọmọ ẹgbẹ fun igbimọ eto ibo ti Apapọ Ijọba pe awọn ko fẹ lati da agbegbe wọn pọ mọ ilu miran ni ipinlẹ Ila-orun Naijiria lati le jẹki nwọn mu enia kan ṣoṣo silẹ lase-ko idibo si ile igbimọ aso fin ti Ijọba apapọ.

### LEOPODVILLE

Ọgbẹni G Mennen Williams to je igbakeji akọwe fun eto alafia ilẹ eniadudu fun Ijọba Amerika si bẹrẹ ọrọ rẹ lati ba Ijọba ilẹ Congo na jiroro lori eto rogbo diyan to sẹlẹ ni orilẹ Congo ati pe bi nwọn yio se tete fi opin si iru awọn iwa to nfa rogbodiyan na.

### ISTANBUL

Igbakeji Arẹ ilẹ Turkish Dokita Kenal Satir ti so ninu ọrọ rẹ pe ilẹ Turkey ti ṣe tan lati da abo bo ilẹ wọn to bati jẹ pe orilẹ na duro gedegbe gẹgẹbi ipinlẹ kan ni Cyprus ti na lọ ati pe awọn yio duro lati fi ara mọ ilu kankan jakejado orilẹ ede aiye.

### GENEVA

Irohin fi ye wa pe ọgbẹni Sukari Tuomioja ọkan ninu awọn ọmọ egbẹ kan ti a npe ni United Nation Cyprus Mediator ni a gbọ pe o fi ara pa eyiti o Jẹ pe o si lewu pupọ atipe rogbodiyan to wa ni ilu na ko ti d'opin rara. Sakari si ti ngbadun bayi.

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYẸ, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 778, MONDAY, AUGUST 24 1964 (2D)


## Ọmọ Okunrin Kan Sọnu

MUSHIN:- Irohin lati ile iṣe awọn ọlọpa ti ile Naijiria de ọwọ wa pe ọdọmọkunrin kan ọmọ ọdun mọkandinlogun Solomon Oh di sonu lati ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi yi ni ile awọn obi rẹ ni nọmba 5 Ogidan Street Mushin

Irohin lati ọwọ awọn ọlọpa na tun fi ye wa pe ọmọ kunrin na Solomon jẹ ẹsẹ marun ni gigun ati pe o si jẹ ọmẹ ti o pupa diẹ, ati pe o tun jẹ enia to sanra!

Irohin lati ọwọ awọn ọlọpa tun fi ye wa pe lati igba ti awọn obi ọmọ kunrin na ti ko ti ri lati ọjọ kẹwa oṣu yi ni nwọn ti lọ fi ẹsun na lọ fun awọn ọlọpa lati ba wọn gbinyanjn bẹya nwọn yio ṣe eto lori ibi ti ọmọ kunrin na gba lọ:

Awọn obi ọmọ na tun fi ye oniwe Irohin wa pe ẹnikẹni to ba le ba wọn ṣe gẹgẹbi nwọn yio ṣe ri ọmọ na pe awọn yio fun l'ẹbun ati pe enia to ba ri ọmọ kunrin na ki o gbin an ju lati lo sọ fun awọn Obi ọmọ na ni nọmba- 5, Ogidan Street, Mushin:

# IJỌBA YỌ ỌBA OLU ILU WARRI KURO LORI OYE

IBINI:- Ni Ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni irohin de ọwọ wa lati ile iṣẹ Alaṣe eto oye jijẹ fun Ijọba ipinlẹ Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe Ọba Erejuwa keji Olu ti Ilu Warri pe nwọn yọ kuro lori Oye ati pe Ijọba ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria tun ni ki Ọba na kuro ni ilu Warri lati lọ ma a gbe ni Ogbesse labẹ Iyekovia ni ẹkun Benin. pe nwọn yọ ọba na lori oye pe nṣe ni gbogboilu dakẹ rọrọ ati pe awọn Ọlọpa si ti mura silẹ ki rogbodiyan na ba ṣelẹ mi ilu Warri

Irohin na fi ye wa lati ọwọ Oniwe irohin ni Benin pe Alakoso eto Ijọba ibilẹ ati eto oye fun Ijọba ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria, Oloye Humphrey ọmọ Ọsagie sọ ni ilu Benin nibi ti o ti nba awọn oniwe irohin sọrọ pe ero lati yọ Ọba na kuro lori oye jade lori eto ti Ijọba ipinlẹ na ṣe ati pe lori iwadi ti Ijọba ipinlẹ yan igbimọ Oluwadi Thomas eyiti abayori igbimọ na jade ti nwọn si sọ pe Ọba Erejuwa keji jẹbi ẹsun ti nwọn fi kan lori owo oko ti awọn ọmọ ibilẹ Itṣekiri eyiti igbimọ na sọ pe Ọba na sọ owo na di tirẹ ti o fi na awọn owo na si aye ati ara rẹ.

Oloye Ọmọ-Ọsagie tun fi ye awọn oniwe irohin pe lori abayọri ti igbimọ na ati eyiti awọn Ọba ati Ijoye ipinlọ na ṣe laipẹ yi ni Ijọba mu ẹsẹ le lati yọ Ọba Olu lori Oye.

ALAFIA

Oloye H. Ọmọ Ọsagie na tun ṣe alaye siwaju si i pe lati igba ti nwọn ti da ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria to ti duro gedegbe fun ara rẹ gẹgẹbi ipinlẹ kan ni ilẹ Naijiria ni ọpọlọpọ awọn ẹgbẹ ti ọmọ Isekiri ti Ijọba ibilẹ ilu Warri eyiti Ọba Olu nṣe alaga rẹ ti nṣe ifisun si Ijọba ipinlẹ na pe nwọn ni lati yọ Ọba Olu ti ilu Warri kuro lori oye ati pe awọn ko fẹ gẹgẹbi Ọba ilu Warri.

Oloye H. Ọmọ - Osagie tun ṣe alaye fun awọn oniwe irohin pe lori ero awọn enia ẹkun Warri ati fun eto oṣin ati alafia fun agbegbe na ni Ijọba na ṣe gbero lati yọ Ọba na kuro lori oye ati pe ki nwọn gbe kuro ni ilu na fun eto alafia ninu ilu Warri.

Alakoso eto Ijọba ibilẹ ati eto oye na tun ṣe alaye pe ohun to mu ki Ijọba ipinlẹ na gbe Ọba na lọ si Ogbesse ni pe Baba Ọba na ni ilẹ nla kan ni ilu na ati pe yio le gba ni aye lati ṣe nkan to ba fẹ ni agbegbe ati pe ki Ọba Eruju wa to jẹ ọba pe o ti fi ọdun diẹ gbe ni ilu na ati pe o si ni awọn enia to jẹbi ati ọrẹ fun Ọba Erejuwa keji ni ilu Ogbesse to jẹ pe o le ba ma gbe pọ ti ko ni fi mọ lara rara pe on kuro ni ilu Warri.

Siwaju sii Oioye H. ọmọ Osagie ṣe alaye pe ki iṣe pe ẹsun ti ile ẹjọ ti kan Olu tabi pe ki Onirunru awọn ẹjọ miran to jẹ pe Oba na ni lati jẹ ni ile ẹjọ giga ti ilu Warri lo mu ki Ijọba fẹ gbe kuro lori oyẹ tabi pe ki okuro ni, Oloye H. ọmọ - Osagie ṣe alaye pe ki tun ṣe pe lori ọwọ oko ti awọn ọmọ ibilẹ Itsekiri ti ọba na ko jẹ lo fẹ mu ki Ijọba yọ kuro lori oye bi ko ṣe pe fun ilu eyiti awọn enia fi nke gbe lati igbati ipinlẹ Agbedemeji ti duro gẹgẹbi ipinlẹ kan ni orilẹ Naijiria.

Ijọba ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Najiria ti yan awọn Oloye mẹrin ti wọn jẹ pataki ninu awọn ọmọ Itsekiri lati wa gẹgẹ bi adele ọba ilu Warri titi nwọn yio fi yan Ọba titun miran.

Ọba Ereju wa keji joye ọba ilu Warri ninu ọdun 1942. Ki eto j'ọba agbẹ lo ti nṣe tẹlẹ ati pe o jẹ ọkan ninu awọn to le jọba ni ilu Benin.

Irohin fi ye wa pe lẹsẹkẹsẹ ti nwọn sọ Irohin

Irohin tun fi ye wa pe ki Ijọba ipilẹ Agbedemeji ipinlẹ Iwọ Orun to ṣe ikede pe nwọn yọ Ọba na kuro lori Oye ni Ijọba ipinlẹ Agbede meji Iwọ Orun ti yan awọn Oloye mẹrin ti yio jẹ Adele Ọba na awọa Oloye na ni, Oloye N. C. Nana, Oloye Odeworitṣe Pessu, Oloye Kubenje Etche ati Ọmọ Ọba Ikeren.

Nigbati irohin na jade ni Benin igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Warri si sọ pe ki nwọn lọ ko awọn ohun to ṣe gbe ati eyiti ko le ṣe gbe kuro ninu awọn nkan to jẹ mọ eto ti oyẹ bi ade ọba, awọn ohun Alumọni miran ti ojẹ mo ti nkan ibilẹ Itsekiri ni awọn Adele na si gba gbogbo nkan na mọra.







Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 24/8/64.